Owe

Adiẹ nỹ'Oke, o om'o-nu, o njẹçongue, on l'ẹran o ni. O ma se o ti on ko ni eino. Kini awọn toni ohun tun ni se? A ngba ọwọ adiẹ Koro Iku. o ni, awọn ko je ki on lo je kokoro lori aiye tun, nitori kokoro gbe nio wuye-wuye.

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

Lakaye Oro

Iwọ ọrẹ mi, ranti pe Ọlọrun n i k a n lo nfun ni lore ti ko nfi laalaa kun. Ibukun mbẹ lori Olododo, iwa rere lo si nmu ni pẹ lẹnu iṣẹ, ki o si b ọ w ọ fun agba, nitori wipe on lo le fun ọ ni igbega ati ilọsiwaju.

VOL. V No. 319 MONDAY JANUARY 1 — JANUARY 7 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# IJỌBA TI KO BA FI TI ỌLỌRUN ṢE, BAWO LO TIṢE LE DA DURO:— SLA

IJỌBA KAN ko le da duro funra rẹ, ayafi ki o ni ibẹru Ọlọrun lọkan rẹ, nitoripe Ibẹru Oluwa ni ipilẹṣẹ ọgbọn, Ilu ti ko ba si ifẹ, eru ati rudu rudu yio gbojikan ailu na.

Ki enia to le ni O m i n i r a pipe, o ni lati ni imọ Ọlọrun alaye lọkan, a sọ ninu Bibeli mimọ pe ẹnyin yio mọ otitọ na, otitọ na yio si sọ nyin di Ominira.

Irohin ti a ngbọ kakiri ilẹ Afrika ni ọrọ bi a o ti ṣe ma huwa bi Onigbagbọ. Kini awọn onigbagbọ orilẹ aiye le se ki a to le gbe Orilẹ ede wa dide larin awọn enia funfun ati enia dudu ti o ngbe iha Gusu Afrika.



Akintọla sọ wipe ko tilẹ da on loju wipe awọn ilẹ Isin igbagbọ ti o mbẹ ni South Afrika mura si ọrọ na wipe kosi ohun ti Oyinbo nṣe ti enia Dudu kole ṣe ati wipe Oyinbo ati enia Dudu jẹ ọkanna niwaju Ọlọrun.

Ani lati tun ile aiye ṣe, gbogbo ọgbọn ori, ọgbọn inu lati ọdọ Ọlọrun wa ni enia ti jogun rẹ, osi yọ ki ẹsin Olodumare gbilẹ lọkan wa Oloye Akintọla lo sọ ọrọnwọn yi ninu Ipade nla kan ti gbogbo awọn Ẹgbẹ Onitẹbọmi ilẹ Afrika ṣe nilu Oṣhogbo lọjọ aipẹ yi, O ba awọn Ijọ na yọ gidigidi.

---

## Awon egbe to nra igo ofifo se Ajodun.

Awọn ẹgbẹ ti Ijọba fun laṣẹ lati ma ra awọn i g o ofifo ta fun awọn Oyinbo ti o nṣe ọti nilu Eko, ti wọn npe ni orukọ yi (The Nigerian Bottles and Tin buyers and seller Association).

Oluwo Onifade Ajanaku ni Baba ẹgbẹ awọn ti o nra igo ta yi, o si pe ipade awujọ nla kan si ọgba ile ere Sinima nita Faji, ninu i p a d e yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Onigo kọwe si B a b a ẹgbẹ nwọn wipe ki o ba wọn di owo igo ku diẹ.

Ṣugbọn Oluwo Ajanaku fi ye w ọ n pe, ki on to le fun awọn ọ m ọ ẹgbẹ lesi ohun kan, o di ninu ibere ọdun Titun, Oluwo tun tẹ mọ wọn leti pe, ki wọn pa ofin ati ilana mọ.

Ẹnikẹni ti o ba si njade lọ ra igo, o ni l a t i mu iwe aṣẹ rẹ d a n i. Awọn ọmọ ẹgbẹ ti ilu Eko niwọnyi:— Ọgbẹni O. O. Ajanaku (Baba ẹgbẹ) Ẹfunnihun Amọkẹ (Alaga) ati Alaba Ajanaku, Iyalu Efunleke, A. Atioba, P. I. Ọdeinde, P. Ṣorunmu, T. A. Oṣu, T. A. Amao, A. Pacheko, Adepe (Balẹ) A. Adeyẹmi (Olori Onikiri) A. M. Ṣolabi



Oloye Onifade Ajanaku

H. Adebayọ (Olori) A. Ọnasanya (Olori) A. Ajanaku A. Igbosami (Balogun) A. Oshodi (Alaga) B. Gbadamọsi (Olori ni Ikoyi) M. C o k e r (Akapo) A. Abẹkẹ (Iya ewe) N, Ajọkẹ (Iya ewe) Ọpọ awọn enia li a fi jẹ oye ti a ko le darukọ wọn.

**E KU EWU ODUN TITUN (1962) TI O BERE LONI**

# ỌRỌ OLOTU

## E ku ewu ibere Odun Titun (1962) ti a bo si yi

A wa Oniwe Irohin Imole fi tọkantọkan wa ki gbogbo enyin Onkawe wa kakiri Agbaiye pe, e ku ewu ibere Ọdun Titun (New year 1962) ti Oluwa jẹki o ba wa laye pẹlu alafia ati ara lile. Ọpẹ ni fun Oluwa, a si dupẹ lọwọ Eledunmare ti o jẹki Odun yi ba wa ni alafia. Bi Ọmọde ba dupẹ ore ana, a si tun ri omiran gba, a wa bẹ Oluwa na ki o pẹlu wa ninu gbogbo iṣe wa ti a ba nṣe, ki o maṣe jẹki a ni ẹjọ ninu ọdun yi, ki o da abo rẹ bo wa.

Gbogbo enyin ti e wa ninu ibanujẹ Oluwa ko tu nyin ninu Oluwa ko da ireti ayọ sinu ọgbẹ yin, enyin ti ẹ nbi abi ku ninu Odun to kọja, e o ma bi abiye ninu Ọdun Titun ti a bọ si yi lagbara Edunmare, enyin ti ẹ si nṣowo ti ẹ ko bode pade, Ọlọrun jẹki ẹ bode pade ninu Ọdun Titun yi o.

A ni mọ Owo, a nimọ Omọ, ibajẹ a dẹhin fun gbogbo wa o, gbogbo enyin ti ẹ ti idale wa ṣowo kakiri Agbaiye, a dele bare, arinna kore, ako ya ibi esu awọgbo, Ọdun yi yio jẹ ire fun wa Amin. Gbogbo enyin urisẹ maṣe ti o jẹ wipe ẹru ẹlẹru ni ẹ nreti lati fi jiiyẹ, ẹ le wa iṣẹ ṣe ninu Ọdun yi o. Ki Ọdun na le dara fun yin, awa ki yio si fi enyin oniṣẹ buruku silẹ lati ibẹrẹ Ọdun yi laiko ma gba nyin ni imọran ki ẹ le ronu piwada ninu iṣẹ okunkun yin.

E jẹki a ranti awọn enia jankan-jankan nilu wa yi ti o ṣe pe wọn ja fun Ominira orile-ede wa, ṣugbọn ti ko soju ẹmi wọn loni, eyi si ni Ọdun Titun keji lẹhin Ominira wa, awọn bi, Herbert Macaulay, Bode Thomas, Adelabu ati awọn bẹbẹ lọ, Oluwa ko gbe wọn sinu afẹfẹ rere, ki o dari ẹṣẹ wọn jin wọn Oluwa Ọgọ Ogo jọwọ a bẹ ọ, rojo anu rẹ si Sare wọn.

Lakotan ọrọ wa, ẹ jẹki gbogbo wa kun fun adura lati ma fi ran awọn Oṣelu wa lọwọ pe Ọlọrun ninu anu Rẹ ki o ma dari wọn si ona rere ninu ipade wọn nilu awọn Alagbara Aiye tabi nihin, ki Ọlọrun si sọ ẹmi gbogbo wa, ki a le lo Ominira wa na pẹ.

## Awon Oselu ile Naijiria lo be ile Gesi wo



Awọn enia mẹta ninu awọn Oṣelu ilẹ Naijiria ti nwọn lọ ṣe abẹwo ilu Gẹsi, ni awọn mẹta ti nwọn duro niwaju Balliol College, oruko wọn niwọnyi: Oloye E. A. Anuku, Oloye Gogo Abbey ati Alhaji Ahman Galadimo Pateji.


ṢỌRA FUN

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro

gbe koro "ASPRO" meji mi

ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA

# Esi Oro Abiodun Ayanda

Lati Ọwọ:- ỌMỌ AKIDẸGBAJU (OKE-ỌLA ORO)

Enlẹ o Abiọdun Ayanda, ẹku aṣaro, ẹku afi ẹnu gba ẹnu, ẹku bi yeyin mọ. ẹkusisi wahu, kinto ma ba ti ọgbẹni Abiọdun Ayanda lọ, mi o se ikilọ, mi na lọ bayi pe gbogbo eniẹni ti o ba fẹ ma sọrọ ninu Iwe Irohin Imọlẹ ki oluwarẹ jọwọ ki o ma darukọ ilu ti otiwa ki araiye gbọ seti, Ọmọ ilu kilu ti oluwarẹ baje ki o jẹki a mọ ninu Iwe Irohin Imọle, iwọ Ọgbẹni Aiyekotọ ki o jọwọ ki o darukọ ilu rẹ ki araiye gbọ seti, ọmọ ilu kilu ti o ba jẹ, ki o jẹ ki a mọ ninu I w e Irohin Imọle Ọgbẹni Abiọdun Ayanda nfi ẹnu gba ẹnu nsọ isọkuso g b a h u lesan, ẹnyin Oke-Ọla-Oro ẹmase jẹki ọrọ ọmọde yi dun yin rara, ọsa ti mọ wọn tẹlẹ, akimowa ilẹ kio kuni ni su.

Ohun akọkọ ti emi yio kọkọ sọ nipa ọrọ Abiọdun yi, ohun oani ọro ọja Oro (Oro Central Market) Abiọdun ni awa Oke-Ọla Oro nbẹbọ ni Ilọrin ki abale si ọja tutun ti akọsi Okeṣẹdo Oro. Moki ọgbẹni yi dada oku bi ọgbọn timọ, oku a i m ọ ọwọ otun yatọ si tosi, moti fi Igbakan sọ fun araiye ninu Iwe Irohin Imọlẹ ti ogunjo oṣukọkanla ọdun yi (20:11:61) pe ki se Oke-Ọla Oro nikan ni nkọ ọja, ki si se Iludun Oro nikan beni ki se Ijomu Oro nikan pulu gbogbo awa ti a ni asojuninu ile Igbomina jọba Ibilẹ Oro (Oro District Council) ti asi jẹ ọmọ ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) awọn Igbimọ na ni wọn paṣẹ pe ki a gbe ọja wa na kuro l'ọtun oro lọsi Okeṣẹdo Oro ni oju taiye lẹwa nba Ijọba ibilẹ Oro fayi, mo

WO IYOKU NI OJU EWE KEFA

# Tafawa Balewa nfe ki a lo ni emi Isin



Ki gbogbo awọn ẹlẹsin Kiriyo, nibikibi ti nwọn ba wa, fi ẹmi ara wọn jin lati fẹ ire ẹnikeji bi o ba jẹ wipe lotitọ ni wọn ni ẹmi igbagbọ nitoripe ẹmi yi ni pataki ninu ẹsin Igbagbọ.

Gbogbo aiye nfẹ i s ọ j i ẹmi ninu isin wa ki a si ni igbagbọ si otitọ ọrọ inu rẹ, bi a ba si fi ara balẹ tẹle eyi, yio ṣe amọna wa lọ kuro ninu iparun. Ọdun owo ọdun ọmọ ni ki ọdun yi jẹ fun gbogbo wa.

# E ku ewu Odun Titun

Mo ki gbogbo ẹnyin Baba ati Iya mi, Ẹgbọn mi ati Aburo mi ati gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe e ku ewu Ọdun Titun, Oluwa ko ṣe Ọ d u n yi ni abo fun gbogbo wa o, ki Oluwa ma ṣe jẹki awa Ọdọ sanku mọ awọn O b i wa loju, ki Oluwa jẹki a gbẹhin awọn Baba ati awọn Iya wa o. Amin.

Kin nto ma ba ọrọ mi bọ, mo ni lati dupẹ lọwọ Baba mi Ọgbẹni Ebenezer Adeniji ti o gba mi l a y e lati ma kọwe lẹkọkan sinu iwe Irohin rẹ oloyinmọmọ mo dupẹ lọwọ rẹ pupọ fun ọgbọn ati oye ti o nfun mi nipa igbesi aiye ọmọ enia.

Mo ki gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ pe, ẹ ku inawo ọṣọṣẹ ti ẹ n r a iwe na, Ọlọrun yio tun bọ ma bu si a p o olukuluku yin, gbogbo ẹnyin ọ m ọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ti ẹ jẹ ọmọ ile Eko bi ti emi, mo ki nyin lọpọlọpọ pe, ẹ ku isinmi ki Oluwa jẹki a peju wọle ninu oṣu ti o mbọ.

Bẹ na ni mo si tun ki gbogbo ẹnyin Olukọ wa lọkunrin ati lobinrin pe, ẹ ku isinmi Ọdun, Oluwa jẹ ki a pade l a y ọ. Lakotan ọrọ mi, mo ki Ọgbẹni Latifu Babalọla ti iṣe akọwe Agba fun ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ẹ ku ewu Ọdun na, Oluwa yio wa pẹlu wa o.



**Adekunle Adeniji** ọmọ Olotu. o si tun jẹ ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye aye rẹ sini: 182 ti o si nlọ si ile iwe St. Peter's Faji School Lagos Nigeria.


BERE OJULOWO EGBOGI WỌNYI:-

## "Congreve Female Remedy"

Gbogbonse fun Itọju tabi Ajo Obinrin fun Inu rirun bedi riro tabi gige nigbakugba, ati oriṣiriṣi arun tabi mọdi ti o ma nyọ Obinrin lẹnu ni Inu nigbakugba.

## "Collomack"

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun Itanpara, awọ ẸSẸ lile, Igbado ẹsẹ ti ki jẹki enia le wọ bata (Corncure) ati oriṣiriṣi arun Ẹsẹ miran pẹlu ni.

## "Mackotal"

Atamatase Egbogi awọn Jamani fun oriṣiriṣi amodi "ETI" riro tabi didun fun ọmọde ati agbalagba bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti pẹ to yio ṣe iwosan rẹ ni kiakia.

## "Meduprival"

Ojulowo egbogi awọn ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ọna-ọfun, Imu tutu tabi ti o ma nsọmi bi ikun nigbakugba, Kẹlẹbẹ ọna ọfun tabi agbari hiha, amurun ati oriṣiriṣi amodi miran gbogbo ti ibẹrẹ rẹ jẹ otutu. Bere ti Ọmode tabi ti agbalagba wọn yatọ nipa agbara wọn ni o

Bere ni Ṣọbu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

# Ajegboro Dagba Nki Nyin o!

Mo ki nyin lomode, mo ki yin lagbalagba, mo ki okun rin kiri o b i n r i n, pe e ku odun e ku iyedun, aseyi se amodun, eposopo odun Olorun jeki ase laiye.

## AGAN IJA BE SILE LARIN ONIWASU PELU ALUFA NI ODUNFA. EYI ARA!

Lale ojo aiomisi nigbati mo sare wa lati ilu Mushin pe ki wa wo iyawo mi, ki fi ara pa die lale ojo yen lati nkan bi ose meji ti mo ti kuro nile, bi mo ti nlo ti mo de opopo Oduola leko ni mo dede ri ero ti won su jo ti won si tun atupa sile gegebi enyin O n k a w e mi ti mo pe emi ko le ri ki ma wo, ni mo ba ya lo woran.

Lehin igba die ti mo de ibe ni mo ba ri ti Okunrin kan dide duro ti o si je Oniwasu ti o bere si soro tibinu, pe bayi lo wa ninu Bibeli pe bayi kosi ninu Bibeli ti ko si fun Alufa layo lati so tire n tori gegebi mo ti se gbo won, nwon ni A l a g a kan to mojuto eto ibere won na, lehin eyi ni mo de ri ti won ju oko kan wa ti emi kosi mo ibiti oko na ti wa, ni ijogbon ba sile o di wipe won ju aga ati oko si ara won, ni mo ba sare ya sinu ile petesi kan ti o wa legbe ibe nitori igi gboran ma gun ni loju ati okere lati be.

Nje oro Agba ni bi ko se lowuro, a se lale, nitorina ara ohun ti mo so ninu oro mi ni nkan bi osu meji se bio ni yi o, wipe ki awon elesin meji ma i ko ara won kise on to ta tabi ti o dara, Ohun ti atako yi ma da sile apa enyin Alufa ati Oniwasu koni ka bi e ko ba lo fi sile ki enikaluku si koju mo esin tire.

Nigbati enyin ba ntako ara yin ti e si tun mba ara yin ja, bawo ni e se fe ki awon Keferi ronu piwada, ninu iwe Olorun ti enyin mejeji nlo, Olorun ko da sile lati ma fi se ariyanjiyan bi kose pe lati ma fi se wasu fun awon onise buruku ki won le ronu piwada ninu ise ese won. Nitorina o di owo enyin Alufa wa, Oseni, Kushoro, Akewukewe, ati bebe lo, ati Oniwasu wa, Adetoro Awosiga ati awon yoku, o di owo yin o.

Nitorina mo fi Oluwa be yin ati Alukurani pelu Bibeli be yin, e lo fi eleyi sile ki e ma wasu fun araiye ki won le ronu piwada ninu ise buruku ti o kun ode oni, emi ko le mo boya awon kan lo koko da sile, nitorina e lo fi sile ki e mase wasu yin lo.

Ki a to mo esin ti o dara ju tabi ti o peju o di owun o di ojo Alikiamo o. Emi ni omo yin Ajegboro dagba.


## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO

MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ti a se ni ase pe fun awon Omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara fun igbona, iko, otutu A i p e r i, Osi Omode jedijedi, kokoro ori Omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu omode ko ma nsun fonfon O mu ki ebin bibu je ise run fun awon omode o ngbe awon omode tobi, tesi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se ma ni fun awon Omode Ijafara lewu pupo, tete lo ra tire ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.




Igo kekere re je 2-6d Igo nla je 4-6d

LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K KARIMU ANJOLA & BROS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria Phone 22515

34, Docemu Street, Lagos Phone 24247


# E ku Odun, e ku Iyedun

# ORO NIPA ANU, ATI NIPA AIGBAGBO

Lati Owo:- WOLI SAMUEL KOGBEREGBE.

Egbo enyin oro mi enikeni to ba nse a n u on na yio ri anu gba, enikeni to ba li eti lati fi gbo ki o gbo IFIHAN ORIN 2, ESE 11. Enyin agabagebe otito li Isaiah so tele nipa ti yin pe awon enia wonyi nfi enu won sun mo mi sugbon okan won jinna si mi, lasan ni won nteriba fun mi, nwon gegi ni won si nfi ori bale fun igi na pelu nwon si w i p e gba mi Olorun.



WOLI KOGBERGBE

Mo fe ki e mo pe enikeni to ba npe igi ni Olorun ti o si fi ori bale fun We re, MATTU ORI 15,- ESE 7 gbogbo enyin enia elo mo pe enikeni to bi, be Oluwa sowo koni padanu, Ka ma ri. Sugbon e mo pe ko si eniti o le gbin Ogede ko ka O b i lori re, Ka ma ri, Nitorina nipa eso won la o fi mo won ki emo pe Igi rere ko le so eso buruku Igi buruku ko le so eso rere, ka ma ri. Olukuluku ni yio so eso tire beni, MATTIU O R I 7 ESE 16, Gbogbo enyin oni sowo mase ba ore da owo po rara, nitori yio fe ara re ju tire lo, Enikeni ti o ba, ba ore da owo po, o ti ba gbese ati wahala da owo po nitoripe ore ko layo le, ti ara re ni yio ma wa kiri. Mase duro de ire enia, duro de Oluwa yio si gba yin. Bi iwo ba fe Jesu, iwo iye Jesu si wipe alabuku li awon otosi li emi nitori ti won ni Ijoba orun alabukun fun li awon eniti kanu nitori won yio ri anu gba, alabukun fun li awon olokan tutu nitori nwon o jogun aiye, alabukun fun li awon eniti ebi npa ti ongbe ngbe si ipa dodo nitori a von o yo, alabukun fun li awon onilaja nitori omo Olorun li a o ma pe won, MATIEU ORI 5 ESE 3. Ore aiye ko se finu han o je lo sora re, nitori bi o ba ni owo lowo ti iwo si ni Moto ti iwo si ko ile pelu, ti iwo si bere si ko omo jade, nigbana ni omo araiye, yio ma wo o sugbon bi iku ba de omo araiye, a sa fun o o nitorina mase duro de aiye, nitoripe egbe ni fun eniti o ba duro de aiye, mo pe ara ile re ni ota re. Mo fe ki e mo pe ari ire-banije li omo araiye. Bo ba dun fun o tan ore aiye yio ma wa o kiri, Bi idanwo ba de ba o iwo koni ri enikan bi iwo ba se ore ti enia m e t a ba mo pe iwo se ore kan fun Samuel ofo ni.

Ohun ti owo otun ba se mase je ki ti osi ko mo omo Ale ko ni wo inu ijo enia Olorun DEUTERONOMI 23 ESE 2.

# Ẹ ku Ewu Ọdun Titun (1962)

## Lati odo Adetokunbo Ademola



Mo ki gbogbo ọmọ ilẹ Naijiria gẹgẹ bi o ti jẹ wipe eyi ni Keresimesi ti o sikeji lẹhin ti a gba Ominira tan iṣẹ ribi-ribi lo m b ẹ niwaju wa lati ṣe bi o ba jẹ wipe olukuluku wa nifẹ ilu rẹ lọkan. Diẹ ninu ohun ti o yẹ ki a ma lepa ni isọkan ilẹ Naijiria, ilọsiwaju i ṣ ẹ ọwọ, ati Owo ṣiṣẹ, idagbasoke ilẹ wa.

Ẹ jẹki a mu imọ tara ẹni nikan kuro, iwọ ni Kobokobo, emi ni Gambari, awa ni Y o r u b a, iru iwa yi ko suwọn. Ọdun owo, Ọdun ọmọ ni ọdun na yio jẹ fun wa. Aṣẹ.

ni asiwaju i l u wa ṣe ndu u lọtun ati losi pe ki ifẹ ati isọkan lẹgbilẹ jọjọ lakoko ti wa yi, lojojumọ ni a nṣe ipade ajumoro, tia si nda orisirisi ẹgbẹ silẹ nitori ki o ma ba si e d e koyede, ati ijọgbọn, a nṣe gbogbo iwọnyi ni tori ki alafia le wa ni ilẹ wa.

## Oloye F. R. A. William Amofin nla



Emi Oloye F. R. A. William, ti iṣe ọkan ninu awọn agba Amọfin ilẹ Naijiria fi tọwọ-tọwọ ki gbogbo ẹnyin ara i l ẹ yi pe lagbara Ọlọrun Olodumare, koni si ogun tabi ija larin ilẹ wa titi ilẹ wa yio fi di ọkan a ko ni ọta tabi ẹtu ṣugbọn awọn akọsilẹ ofin ti awọn Gẹsi fi kọ wa ni yio jẹ ọta ati ẹtu f u n wa, pẹlu O g o ti Ọlọrun, ẹgbẹ O l ọ p ẹ yio sọ ilẹ Naijiria di ọkan.

## Lati odo Alaiyeluwa Oba Adele Keji Eko

Moki gbogbo ẹnyin ọmọ Eko wipe ẹku ọdun, ẹku Iyedun, Ẹnikẹni ti gba pe, ko si ilu ti a o fi Eko we.

Bi a ba yọwọ ilẹ Egypt kuro kosi ilu kan ti a le fi we Eko tabi ilẹ Naijiria a mbẹ Ọlọrun ki a maṣe jẹ ki ilu Eko bajẹ fun wa o.

Ṣugbọn ni wọn igba ti oju ko ba ti Ẹhingbẹti, o daju [illegible] oju ko le ti Eko. [illegible] yi ko ni bajẹ fun [illegible] ko ni ku lọmọde, a ko ni [illegible]gba esi, siwaju siwaju ni ọpa [illegible] yio ma re si iwaju [illegible] a o ma lọ o. Amin.

Ọdun Keresimesi fi ye wa wipe aiye alafia yio wa ni akoko ti wa, nitori na



**Eniti a nwo loke yi ni Alayeluwa Oba A d e l e Keji ti ilu Eko.**


BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ehin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ rirun, rukuruku Pipọn tabi rirun, lakuregbe, Ibara di wiwo, ornnkun, owọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugbe, ati orisirisi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria ni.orina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbirọbi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba a rara o! Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ ṣile meji abọ (2/ 6d)



Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

OBERE LATI OJU EWE KETA

wafe Iiye Abiodun koya en je omode ninu oselu Otun Oro, awon Councillors ti gba ase lati Ilorin N. A. Council gege bi oro pe awon fkranyo ki won gbe oja otun oro lati Okeodo Oro, ki won si ma na oja na ni ojo oja Oro ni orisun, Emi omo Aridegbaju wa fowo so aiya gbangba pe, ni agbara Olorun oba, Oba wi be jebe mo wa wo oja, mo wo isale ni o ri ohun ti o le di oja yi lowo tabi dadura ki o ma je sise mo, ojo oja ti a na oja Oro ni a o si ma na pelu ola alale Ekunmesan Oro owo ko ran, ogun koran, ko da Ogbeni Balelayo Onisango yin ti e gba nitori oro Oja yi ko di wa lowo rara, ehyin papa na yio na oja yi pelu, ti e ba si pe lati da po mo wa e o san owo iso, niowuleto eboro ti ba ugbisin sole yio wulete, lyeabee Abiodun ni ki ilu oke-ola Oro lowo lokudi, esi mi fun eyi ni n i p e awa konimu lokudi rara; bi o ti e jepe otito ni emu lokudi ope fun yin se, kini a o fi Lokudi se?

Awa ti a si alaikurani mimo lowo ki awa sope a pe Olorun ko da wa lohun ko a bi bawo? Olorun ti nda wa lohun ni gbogbo igba ko ni pada lehin wa laelai Amin Oja kun faya kun Olorun Oba. Abiodun ni aparo ati ejo lati waka nibi oja ti anna loju de Ogbeni Paul, Abiodun yi puro ni, akotuka sugbon awon ara Otun Oro ran eiye sita siwa letito, gege bi enyin Ile Igbomina timo awon ara Otun Oro yi si, elemi esu ni won, won gba ologun kan, orako re amaje bale layo oni sango ni ogbeni na. Ogbeni yi ni ki won mu owo apomarun wa (£500) ati malu meji (Two Cows) oni biwon bati fun on ni okan won, oja baba gbogbo wayi konikuro ni Otun Oro mo lailai, mooi iro ni iwo Ogbeni Balelayo yi pa,

WO IYIOKU NI OJU EWE KEJO

## Awon jamba to sele lakoko Odun Keresimesi

Opolopo jamba lo s e l e, lakoko ti a nyo ayo Odun Keresimesi kakiri i l e Naijiria ati papa kakiri agbaiye ninu awon jamba to sele nilu Eko, jamba medogbon lo sele ni Eko ati agbegbe re: Awon omo olodun kan ti won nje faaji odun lo kakiri ni jamba sele si moto won, tobe ti awon enia meji fi ku bamubamu, ti ogoro awon enia si fi ara sese. Ninu awon enia ti o ku ni Charlie Ingele ti o nta iwe irohin, to si ngbe Mushin Adeyola Adebi, ti o ngbe Ita Olokodana ni ona Ijero a gbo wipe Dereba Taxi to pa okunrin to nta iwe irohin salo, awon Olopa si nlepa re.


## A ki Enyin Onibara wa o!

Ogbeni Alagba wa A. K. Karimu Anjola tise Oga ibiti a ti nta egbogi Oyinbo fun awon Omode eyiti won npe ni Mogbayi Cough and Baby Mixture, ti won polowo re si iasle oro yi, ki gbogbo enyin Onkawe Irohin Imole ati awon Onibara wa kakiri ile Naijiriria ku ewu alaja odun Keresimesi ati odun titun 1962. Emi gigun ati Alafia ara ki Oluwa fi ta wa lore ninu odun yi, ki a ma pade agbako, lowo iku ojiji Oluwa rere gba wa o. Odun owo, Odun omo ni odun na yio je fun wa.

A fi eleyi ran yin leti pe egbogi wa na ti de fun ti ta fun odun titun nitorina ki o tete wa ra tire ki o to tan.

Awa ni

**A. K. KARIMU ANJOLA & BROS**
**6, Balogun Street, West, Lagos.**



OBANGBA DEKUN! KEDERE BEWO!!




OLUBORI EGBOGI "IKO

# THIOLYPTINE

Bi amodi "IKO" ti ojo reti pe tabi ti o nyo o lenu fun nkon bi odun kan tabi jube lo awon egbogi robirobi ko le se iwosan re rara, ma fi owo re se Ofo mo

Bere fun egbogi awon ara Ilu Faranse ti won npe ni Thiolyptine ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun, Iko here, Iko etutu, Iko ona ofun, Iko Igbaaiya, Iko lile, Iko, ti o ma mu enia to kelebe nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lunes) tabi ti o ma nmu enia ru pelu. Bi o ba dan Igo kan egbogi Thiolyptine yi wo, Iwo na yio ri iyato ninu ara re ni kiakia, Igbaaiya tabi ona ofun re ti o ma nho yio dum, "IKO" re yio si san patapata, iwo yio ma jeun duradara iwo o si sun fonfon pelu alafia de.

Bere egbogi yi ati awon orisirisi Egbogi Iko miran ni Sobu awon:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET, YABA
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.



## MOGBAYI COUGH MIXTURE




Mogbayi Cough Mixture je Ogun Iko pataki ti a se ni asepe lati wo awon Iko orisirisi san ni kiakia. O dara fun Iko agbalagba ati Iko omode beni o si tun dara fun Iko omo owo pelu.

O dara pupo ju gbogbo ogun Iko yoku lo. O dara fun awon arun Iko wonyi, Iko ti o ma nha enia ni ohun, Iko ti o ma npon enia loju, Iko ti ki jo ki enia sun dada, Iko ti o ma ndun enia legbe, I k o ti o ma nta enia ni aya, Iko ti o ma nfa Efori, Iko ti o ma nfa are ba ara, Iko ti o nmu ki enia ma po eje, ati awon Aisan m i r a n ti won somo Iko bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupo fun enyin ti Iko nyo lenu, E ma se sahun fun alafia ara yin, alafia ni opin oro ijafara ni ewu pupo, tete lo ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo re, Igo kan re je 2/6d' arapo re je 24/-.)

**LILO RE:-**

Omo osu meta—Idaji sibi tii kan ni wakati metameta
Omo osu meta si mejila - Sibi tii kan nigba meta lojojumo
Omo odun kan si mefa.- Sibi tii meji nigba meta lojumo
Agbalagba..............Sibi Imuko kan nigba meta lojumo

*Whoesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

| | |
|---|---|
| 6, Balogun Street West<br>Lagos, Nigeria.<br>Phone 22515. | 34, Docemu Street,<br>Lagos.<br>Phone 24247. |

# Oro ati awon Ilu Iyoku

Lati Owọ:- TANIFEANI (ORO)

Lati nkan bi ọsẹ diẹ sẹhin ni awon ọrẹ mi ara Oke Ora ati Iluju ti nsọrọ nipa Q j a Ọtun oro ti wọn fẹ gbe kuro lọsi Okesedo. Se Ọlọrun kosi ni ẹhin alabosi oro na wa di oloyipo oti wa yi po mọ ara Iluju ati Oke ọra lọwọ wọn kori ọja gbe kuro ni O r o apati ara lonta wọn. Ni awọn ọrẹ mi na w a ki gbe pe ara Oro nle awọn ọ m ọ awọn se ti onisẹ ba so iṣẹ rẹ ti ko ba si fẹ ọmọ ọdọ morope iyan kise ẹsẹ awọn ọrẹ mi ara Iluju ati Oke Ọra wọn wa sọ ara wọn di Alla tulasi won yan Bibeli wọn yan Alukurani wọn ti wa gbagbe pe ẹlẹsẹ koni lọ lai jiya ẹsẹ ẹsan lode ba yin nipa ero irẹlẹ ti ẹro si Oro Ọlọrun si ngbe Oro ga ẹnyin ara Iluju ati Oke Ọra o wa to akoko fun yin lati mọ Oro ni Baba yin kẹwa lati tuba fun Oro.

E mase se Ọ r ọ yin ni Ajẹ Ogbodo ti wa ni Kunra kini ti Oke rimi nibẹ kini o wa kan Ijọmu, Ẹnyin Iluju ati Oke Ọra ni ti o ba rẹ yin kẹ wa tuba fun Oro Oro ni baba yin aoẹrẹ bọ l ọ w ọ adẹtẹ oku ati be ope ti awọn ti nsọ isọkusọ pe Lukudi ni ara O r o nlo nje awọn Olowo Oke Ọra ati awọn Olowo Iluju Lukudi ni awọn na nlo ni yẹn.

Iwọ to sọ bẹ osi ti opa B a b a rẹ na ni yio pa iwọ ọmọ na Igbati iwọ wa ni Talaka to si tun sẹgan Olowo osọrọ ọja ti ẹ ṣe ni aṣe ti, to kole kuro ni Oro mo lailai iyen ko to ironu fun yin lati igbati ẹti nawo nara mo gba pe ọmọ ale ni nym.

O sọrọ ọja o tun sọrọ Iyawo ti osi ti ndamu rẹ ti ko ba pada lẹhin rẹ wa lọ si ọdọ awọn Ọrẹdọla lati lọ se ọmọ ọdọ lọdọ wọn ni iwọ koni Owo, oni iwọ yio da nkan kini o fẹ da ju were lọ sọ orukọ rẹ ki Ọrẹdọla si tun gba Iyawo rẹ na ki a wa wo olun ti iwọ na yio da.

# Ololа Gomina Agba Dokita Nnamdi Asikiwe ki gbogbo enia ku ewu odun Keresimesi

Mo ki gbogbo ẹnyin ara ilẹ Naijiria wipe ẹ ku ewu ọdun keresimes, ẹkanṣoṣo li ọdun larin iru ọdun bayi kakiri agbaiye. a si nfi ọdun na ṣe ayọ ati iranti ọjọ ibi Jesu, ẹniti a bi sinu Ibujẹ ẹran ninu abule kekere kan ni agbegbe Bẹtilẹmu niwọn ẹgba a ọdun ẹhin.

Ifẹ inu rere si enia laiye ifẹ alafia, eyiti awọn Kiriyo ma nwi, ko ṣe aroso rara, bikoṣo otitọ ati ododo ...



Akopọ Ifẹ ati inurere yi lo le sọ aiye yi di ohun ti o dara fun enia lati ma gbe. Bakana nileyi, a le ṣe iranlọwọ ki a le di ẹni nla nipa pe ki a lakaka lati de iru ipo bẹ. Bawo ni a ṣe le ni ifẹ inurere yi ni aiye igba rudu rudu yi ti kosi otitọ kan ati ododo rara, ti ẹnikan ko si le ru ẹru fun ẹmi keji. Bawo ni a ṣe le g a Jesu gbọ, ki a si kọ ofin ati ilana rẹ silẹ, bi a ba ṣa bayi, a ko nṣe Onigbagbọ ododo. Ẹjẹki a fi igbagbọ wa rinlẹ gbọingbọin, ki a si ma bọwọ fun awọn agba, Mo ni ireti wipe, awa gẹgẹbi Onigbagbọ ilẹ Naijiria, nigbati aba nṣe iranti ajọdun ọdun Keresimasi bayi a ko ni gbagbe bi ọdun na ti ṣe ṣẹlẹ, ki a maṣe lo gẹgẹbi wipe, a bi Olugbala fun nyin loni, ẹniti iṣe Imọlẹ ati Iye, ṣugbọn gẹgẹbi ọna titun sinu Iye. Niti wipe ọmọ enia nsubu sinu ẹṣẹ lojojumọ ko tọ ki eyi jẹ ifasẹhin fun awọn Onigbagbọ. Nitorina ẹnyin enia mi, nigba kigba ti a ba ayọ ti inu wa si ndun, ẹ jọki a mọ lori kini a nyọ le loni. Nitorina mo ki nyin pe ẹ ku ewu ọdun Keresimesi to kọja lọ yi, ẹ si ku ewu ọdun titun loni.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

## "DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa rinṣẹ si awọn Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mo daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri sugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara tabi ki o ma le sun de wọn lọsan tabi loru tabi awọn "iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹ ẹmi (breath) inu ko ba gunle dara kara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ ko "NJẸ" fun wọn ailera gbogbo wọnyi ti ojo ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn o d u n lọ si dede adorin tabi jube lọ mọ daja pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ y o ma gbe konkon nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio silọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na n Ṣọbu awọn:

**Waterlco Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

### OBERẸ LATI OJU EWE KẸTA

ogun akoko ti okunrin yi kọkọ se fun wọn nipe oran aparo kan siwa, nigbati aparo yi side lotito, koiti ba ti ati gan lese, erekose ni atu e p o motor si, asi sun aparo na, mowa sofun awon enia mi ni ojọ na lọhun pe, ki wọn ranti ohun ti Ọlọrun sọ ninu Alukurani mimọ pe, Alasina yuminu bi lahi wara sulihi la aofu alehi walehun yah sah nuna Ọlọrun Oba ni gbogbo ẹnikẹni ti o ba gba ori Ọlọrun gbọ, ti o si gba Anọbi Muhammad ojise ori gbọ pelu, ti o paya ori Ọba na Ọlọrun ni ki oluwarẹ mase bẹru, ki o mase sojo, kosi ifoya mo fun oluwerẹ kini awa yio maberu aparo tabi ejo si?

Lotito awa koni ogun sugbọn ani Ọlọrun Oba, ọba ti o da ewe ati egbo ọba ọrun on Aiye (Allah Hu Akibar) Iyẹabọ. Abiọdun ni Ọlọrun da awọn lọla, adupe lọwọ Ọloron na, sugbon k o s i ibiti Ọlọrun kose ọla si. bi Ọlọrun ti dara si Ọtun – Oro bẹna lodara owo si Oke Ọla Oro pelu, Olowo wa ni Ijọmu Oro, o wa ni Iludun ati ni agbo Ola Oro, o wa ni Afin Oro, gbogbo orilẹ aiye ni oloso wa, kosi ilu ti Ọlọrun da ti ko da olowo sibe bi o ti wu ki o le mọ, ọrọ Omugo wani lati sọpe ilu Ọtun Oro lo la Oke-ọla oro loju ki wọn to di olowo. Ọlọrun ọba ni fun ni lowo ati ohun gbogbo laiye ati ọrun, adura mi si gbogbo ẹkun mẹsẹsan Oro nipe ki Ọlorun mase jẹwo ike rẹ lara wa, ki o si tun mase alekun ore re fun wa pelu, ki ore na wa kakiri gbogbo ilẹ Igbomina. Amin. Abiọdun ohun ti awọn enia fi nsọ pe boya Jukudi ni ẹnyin ara Ọtun-Oro mu nipe bi ọrọ koiti to ọro ẹ o ma gba Ilọrin lọ, pẹlu owo iye biye, ẹ o ma ra moto ayọkẹlẹ e tun fi owo epo ti, se bi ti enia ba ni owo lọwọ ilu ẹni la fi tun ṣe, ẹ fi ọba Oloro sile ẹ ko ra moto fun, ẹ nra moto fun ẹni ẹlẹni.

Mowa bẹ ẹnyin ara Oke Ọla Oro ẹ mase binu ki ẹ ma ba si wa hu, mo fi ori ọba Elẹso, ọba Onikeye aburo Aiyesesin, ọba Aiyerinmoye, ọba Aridẹgbaju ati bẹbẹ lọ bẹ yin, Ọlọrun koni kọ di aimọṣe si yin adura yin pe ki ẹkun mẹsẹsan Oro di ọkan soso pẹlu ogo Ọlọrun, gbogbo ẹkun mẹsẹsan oro ni temi ọmọ Aridẹgbaju Ọlọrun koni ba ọkan jẹ nibẹ. Odigba kan na o.


ỌRỌ NIPA ṢỌBU AWỌN SARO TI WỌN NPE NI

## Waterloo Medicine Stores

TI O WA NI NO. 8, PALMCHURCH STREET LAGOS

Wọn bẹrẹ si se owo egbogi lati ọdun 1930 titi di oni.

Ninu gbogbo awọn egbogi ti wọn nta kosi aṣanu tabi rọbirọbi ninu wọn rara papa awọn Tọniki, egbogi ọmọde tabi fun Ọ m ọ Ọwọ lati bu chin laisi wahala irora tabi iyonu rara fun awọn abiyamọ ti wọn npe ni "Tessydre" lati ilu awọn F a r a n s e, bẹsi ni orisirisi egbogi wa fun "AJO" obinrin ti amodi inu ba nyọ lẹnu ti yio se iwosan rẹ bi danga, Egbogi fun "ARẸ ARA" fun Ọkunrin wa lọdọ wọn ni orisirisi ti awọn aboyun Toniki ko ti o ni onka wọn pọ lọ jaburata ni. Egbogi "ETI DIDUN" ti o daju, Lakuregbe, Ikọ ati orisirisi arun ara gbogbo. Awọn ara Oshogbo ranṣẹ fun awọn Elegbogi wonyi pe ki wọn wa si Ṣọbu si ibẹ wọn si ti fi ọkan da bẹ lọla ni No 11 A Fagbẹsa Street ni Ilu Oshogbo ẹsinsinyi. Ọrẹ mi, majẹ ka tan ara wa jẹ mọ meji iru Ṣọbu ti o ni iru awọn egbogi wọn kosi ni igboro ilu Nigeria awọn Oyinbo-Ṣọbu elegbogi mọ daju bẹsi ni Ṣọbu awọn enia dudu mọ pelu. Afi iwe kekere yi ki oga awon ṣọbu elegbogi na pe wọn ku ọdun wọn ku iyedun iṣẹ wọn yio wa lọ siwaju ati siwaju o amin. OLOTU.

DIRECT ALL YOUR PRINTING JOBS TO:—

## MODUPE PRINTING PRESS

16, BAMGBOSE STREET LAGOS

Phone: 21985


Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Oloru E. A. Adeniyi. 51, Tẹjuoṣho Street, Suru-Lere YABA.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI W ỌN PE NI:-

## RICHALET

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yatọ patapata si awọn Robi-rọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" bi Mọnọmọnọ.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku, adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo, Iyọn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti a nranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, F a r a n se, ati ti awọn Tatabulu si Itali jẹ. Mọ daju pe bi Ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ. Lakuregbe, orisirisi Inarun Ojuṣiṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Aya didun Itanpara, ekuru lara.

Ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apo ile itọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Riṣaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ẹ j ẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ ara rẹ mọ tonitoni pẹlu. Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹ l o m i r a n pẹlu nigbakugba.

Bere egbogi yi ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

## KERE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Ẹku afojuba egbogi pataki ti a ṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialist) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o ṣọpọ ni sisinyi papa ni arun awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ TULU LUKULUKU, OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO. ati OTUTU ORẸRẸN pẹlu AKOKORO Jọwọ danwo ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to afojuba Bere iwe ti ẹ o fi lọ lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin: O daju hanwun. Ẹ o ri iṣẹ rẹ lẹhin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lo Bere lọwọ Oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Sreet Phone: 23745
LAGOS